UK Health
Security
Agency

NHS

# M M R

ÌTA | IBÀ ÀTI ÀPÀ-ÌTỌ WÍWU TI O LE GAN | ÌTA PÍPỌ́N









# ABẸ́Ẹ́RẸ́ ÀJẸSÁRA



**Ojú-ewé yìí ń s'àlàyé nípa àrùn ìta, ibà àti àpà-ìtọ̀ wíwu ti o le gan àti ìta pípọ́n àti àjẹsára MMR èyítí ó ń ṣẹrànwọ lati dábòbò gbogbo awọn aisan mẹtẹẹta.**

**G bígba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára**

Síṣe iranwọ lati dábòbò gbogbo eniyan,
nigbogbo ọjọ ori

M M R

ÌTA | IBÀ ÀTI APO ITO WIWU TI O LE GAN | ÌTA PÍPỌ́N

# Kínni ìta?

Ìta jẹ ailera àkóràn gidigidi ti kokoro ailefojuri èyítí ikọ ati sísín ń ràn. Bí o kò bá báàbòbò ara ré tí o si ni ifarakinra pélu éniti o ń kója ti o si ni ìta, o seeṣe kí ó kóo ràn ọ pẹlú. Bí o ba ko ìta o seeṣe ki o má ṣe daradara ti ó si pa ile-ẹkọ tàbí iṣẹ jẹ fún bíi ọjọ mẹwa. Kọsí ìtọju tàbí iwosan kankan fún ẹyi.

**Àwọn ààmì àrùn** ẹyi ni ibà, ojú ẹjẹ pípọn, and ara sísú. O le jẹ àkóràn lílé fún àwọn ènìyàn mìíràn.

Ó seeṣe kí **àwọn Ìdíjú** ṣẹlẹ láàrin àwọn pàtó ẹgbẹ eyiti o pẹlu àwọn ènìyàn pẹlu ètò ara alailagbara, àwọn ìkókó tí kò tíì pé ọdun kan ati àwón olóyún. Àwọn ìdíjú le jẹ àwọn ìkọlù àyà ati etí, ìṣe déédéé, igbẹ gbuuruu, ìkọlù ọpọlọ ati ọpọlọ bibajẹ. Àwọn to ba ni àwọn ìkọlù le nilo lati wà ni ile-iwosan fun itọju.

**Ṣé ó lé?** Bẹẹni, bíi ọkan nínú ẹgbẹrun marun eniyan pẹlu àrùn ìta lo seeṣe ko ku atipe lati ọdun 2006, iku lati ọdọ ìta mẹta lo ti wa ni orilẹ-ede England ati Wales.

## Kínni iba àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan?

Iba àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan jẹ aisan kokoro aifojuri to n tan kalẹ nipa ikọ ati sisin tabi ifarakinra pẹlu ẹnikan to ti ni aisan naa.

**Àwọn ààmì àrùn** ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan  má ń sábà lo ọsẹ meji o si le jẹ ori fifọ ati ibà sugbọn ààmì àrùn tọ wọpọ ni àwọn ìsun wíwú ní ẹgbẹ ojú. Eyi le fun ọ ni irisi nini 'oju fótofòto' ó sì le fa inira ati isoro igbe nkan mi.

**Àwọn ìdíjú** ibà àti apo ito wiwu ti o le gan le jẹ inira o si le pẹlu oju ara wiwu, ati oronro nigba miiran. Iba àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan le fa àrùn akoran ọpọlọ wiwu ati àrùn ọpọlọ Biotilẹjẹpe iditi patapata lẹyin ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan kò wọpọ, bíi ọkan ninu ogun eniyan to ni le ma gbọran fun igba diẹ.

Kòsí itọju ogun kankan fun iwosan ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan lọwolọwọ ẹwẹ itọju wa lori dindin awọn ààmì àrùn kù. Bí o ba ni ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan o seeṣe ki o nilo isínmi ori ibusun ati apooro inira l'akoko yìí. O le nilo lati ma jẹ àwọn ounjẹ rirọ ti ko nilo jijẹnu pupọ. Irú àwọn ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan tí ń mú àwọn agunbanirọ ti ko tii gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR mejeeji.

## Kinni ìta pípọ́n?

Ìta pípọ́n jẹ ailera kokoro aifojuri, ti a n saba pe ni ìta Jamani, eyiti o sọwọn ni orilẹ-ede UK ọpẹ fun aṣeyọri abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR. O ma n ran ni ọna kanna bíi ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati ìta. Fun ọpọ eniyan, o jẹ ipo ti ko le pupọ to le sàn ni ójó meje si mẹwa laisi itọju. Ẹwẹ, bi alaboyun ba ni ìta pípọ́n o le lewu pupọ fun ọmọ inu wọn.

**Àwọn ààmì àrùn** ìta pípọ́n ni ara sísú, àwọn ààmì otutu ati orikerike ara riro.

**Àwọn ìdíjú** ìta pípọ́n kò wọpọ sugbọn bi alaboyun ba ni ìta pípọ́n l'akoko iloyun, atubọtan buburu le wa fun ọmọ inu rẹ eyiti o le ki o bi ọmọ naa pẹlu àrùn ojú, eti dídi, aisan ókàn tabi ọpọlọ bibajẹ.

## 1 Abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára kan

abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR jẹ abẹ́ẹ́rẹ́ kan ti a n gun awọn ọmọde ni itan tabi oke apa ọmọ toti dagba tabi agbalagba. O jẹ abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ààyè eyiti o tumọsi pe o ni ẹda awọn kokoro aifojuri ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n alailokun, Àwọn wọnyi ti di alailagbara to lati pese àjẹsára lai fa àrùn.

## 2 Abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára meji

àjẹsára MMR n fun ni l'aabo pipẹ pẹlu abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára meji. Abẹ́ẹ́rẹ́ akọkọ ń jẹ gbigba ni ọjọ ori osu kejila ti abẹ́ẹ́rẹ́ keji si ma jẹ gbigba ni biiọmọ ọdun kẹta ati osu mẹrin, saaju ibẹẹrẹ ile-ẹkọ. Gbigba abẹ́ẹ́rẹ́ mejeeji n funni ni aabo pipẹ tako àrùn ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n. Laarin awọn agba ati ọmọde toti yọrun àwọn abẹ́ẹ́rẹ́ mejeeji le jẹ gbigba pẹlu ààyè osu kan laarin wọn.

## 3 Àrùn mẹta

abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR n gbogun ti àwọn arun mẹta; ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati íta pípọ́n. Wọnyi ni àrùn kokoro aifojuri to le yara ran awọn ọmọ ati agba ti ko l'aabo - wọn ma n ran pẹlu irọrun ju ajakalẹ àrùn tabi fikinfikin lasan lọ.

## » Ààbo to pẹ

àjẹsára MMR lo l'aabo julọ o si jẹ ọna to munadoko lati dábòbò ara rẹ tako àrùn ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan àti ìta pipón. Lati igba ti abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ti de ni ọdun 1988, àwọn ipo yii ti sọwọn ni orilẹ-ede UK. Ẹwẹ, ajakalẹ arun, paapa julọ ìta, ti sẹlẹ nigbati iye awọn to n gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa dinku. Ti ko ba da ó loju boya o ti gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa tẹlẹ tabi bẹẹkọ, ole yẹẹwo pẹlu GP rẹ, gbigba abẹ́ẹ́rẹ́ miiran ko le ṣe ijamba kankan.

# Tani o yẹ ki o gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára naa?

## Àwọn ọmọ wẹwẹ

O yẹ ki awọn ọmọ wẹwẹ gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára naa gẹgẹbi eto igba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára gbogbogbo ti orilẹ-ede UK. Wọn yoo gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára meji, akọkọ ní kete ti wọn ba ti ṣe ọjọ ibi akọkọ ati abẹ́ẹ̀rẹ́ ẹkeji ki wọn o to bẹrẹ ile-ẹkọ - paapaa julọ ni ọjọ ori bii ọdun mẹta ati osu mẹrin

## Awọn agba ọmọ, agunbanirọ ati ọdọ

Ti o ko ba tii gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára MMR sẹyin tabi gba ọkan ninu rẹ, o gbọdọ kansi alabẹ GP rẹ lati s'eto àti gba ajẹẹlẹ abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára rẹ. Bi o ba ti gba ọkan ninu abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára MMR gẹgẹbi ọmọde, o kan nilo lati gba abẹ́ẹ̀rẹ́ kan si, ko niiṣe pẹlu bi akoko gbigba abẹ́ẹ̀rẹ́ akọkọ ṣe pẹ to. Bi o ba nilo abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára meji o le gba laarin alafo osu kan si ara wọn.

## Àwọn obinrin to wa ni ọjọ ori ibimọ

Ìta pípọn le jẹ àrùn lile fun awọn ọmọ inu, o le fa ifọju, iditi, ati iku paapa. Bi o ba jẹ obinrin to wa ni ọjọ ori ibimọ, koda ti o ko ba s'eto lati ni ọmọ, o gbọdọ gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára MMR meji saaju ki o loyun. Bi o ko ba tii gba abẹ́ẹ̀rẹ́ meji, tabi ko da ọ loju, o gbọdọ kansi alabẹ GP rẹ lati s'eto àti gba ajẹẹlẹ abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára rẹ. Bí o ṣe jẹ abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára ààyè, o gbọdọ yago fun nini oyun ni osun kan lẹyin abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára nitorina o gbọdọ lo ifetosọmọbibi to daju lasiko yii.

Bí o ba l'oyun tabi ni ọmọ kan ko si da ọ loju boya o ti gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára MMR, ba GP rẹ sọrọ tabi akọṣẹmọṣẹ nọọsi rẹ ni ayẹwo ọsẹ kẹfa lẹyin ibimọ rẹ.

## Awọn agbalagba

Awọn Agba ta bi si orilẹ-ede UK saaju ọdun 1970 seeṣe ki wọn ti ni arun ìta, ibà àti àpò ìtọ wiwu ti o le gan ati ìta pípọn rí gẹgẹbi ọmọde tabi ti gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára ìta tabi ìta pípọn ẹyọkan eyiti wọn lo saaju ki MMR to de ni ọdun 1988.

Bí ko ba da ọ loju boya tabi o ko tii ni awọn arun yii ri tabi gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára lati dábòbò tako wọn, o le bi GP rẹ leere lati fun ọ ni àjẹsára. Ó nilo abẹ́ẹ̀rẹ́ meji, alafo osu kan laarin wọn. Koda bi o ba ti gba abẹ́ẹ̀rẹ́ àjẹsára tẹlẹ, o ko ni wa sinu ewu bi o ba gba afikun abẹ́ẹ̀rẹ́ bioṣejẹpe eto igbogunti ara rẹ yoo ranti yoo si yara ba awọn àjẹsára kokoro aifojuri naa jẹ.

## Nję ęyin odi ni wọn ti bi ọ tabi tọ ọ dagba si?

Bi wọn ba bi ọ tabi tọ ọ dagba ni ẹyin odi o le nilo abẹ́ẹ́rẹ́ MMR meji. Ọtọọtọ awọn orilẹ-ede ni awọn eto àjẹsára ọtọọtọ kiisi ṣe gbogbo wọn lo n lo apapọ abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR. Bí o ko ba ni akọsilẹ abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ti o ti gba tabi ko da ọ loju, ba GP rẹ jiroro eyi. O le nilo awọn eto àjẹsára miiran lati dábòbò ọ lẹkunrẹrẹ lọwọ awọn arun miiran.



## Bawo ni abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa se n sisẹ?

**abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR jẹ ààyè àjẹsára to n gbogunti ìta, ibà àti àpò ìtọ wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n ati ìta pípọ́n. abẹ́ẹ́rẹ́ ni o fi gba awọn àjẹsára meji sinu ẹsẹ tabi oke apa. Eto igbogunti ara rẹ n dahun si àjẹsára naa nipa pipese awọn sẹẹli to le mọ ati ranti ọkọọkan àwọn kokoro aifojuri mẹta. Bi o ba salabapade ọkankan ninu awọn arun naa ni ọjọ iwaju, awọn sẹẹli wọnyi yoo ji dide wọn yoo si ji ara rẹ lati pese oje ara ti yoo tako wọ ni kiakia. Ààbò yìí ma n saba pẹ.**

## Bawo ni abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ṣe wa ni ailewu si?

Apapọ abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ti n dábòbò awọn ọmọ fun ọpọlọpọ ọdun ni ọpọlọpọ orilẹ-ede agbaye. Ni orilẹ-ede UK, ọkẹ aimọye abẹ́ẹ́rẹ́ la ti funni bíotijẹpe ọdun 1988 lo de. Ki abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára to le jẹ lilo, a gbọdọ ti s'ayẹwo fun aabo gidigidi. Biotilẹjẹpe ààyẹ kọọkan lati eto igba abẹ́ẹ́rẹ́ ajésara le wa, wọn ma n mọ niwọn wọn ko si le to awọn arun naa funrawọn. Awọn iṣesi ara lile to ma n tẹle igba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára sọwọn.

Ọpọlọpọ iwadii ti waye lati wo aabo ati imunadoko abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR. Ẹri naa f'oju han pe ko si isopọ kankan laarin abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ati abirun.

## Bawo ni o ṣe n sisẹ?

Bẹẹni, abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa dara pupọ ni pipese aabo tako ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n.

Ju ida kan din lọgọrun awọn to gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára meji lo ma l'aabo tako ìta ati ìta pípọ́n. Biotilẹjẹpe ààbò ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan rọra keere, isẹlẹ laarin awọn eniyan to gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ko le pupọ.

A s'afihan MMR ni orilẹ-ede UK ni ọdun 1988, o si wa sọwọn fun awọn ọmọde lati ni awọn arun wọnyi. Ajakalẹ arun ìta, ibà àti apo ito wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n ti wa ni awọn ti ko pẹ. O seeṣe ki wọn sẹlẹ nigbati awọn ipele igba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ba lọlẹ, sugbọn wọn le sẹlẹ nigbakugba o wa ṣe pataki lati rii pe o dábòbò ara rẹ nipa ninu abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR meji.

## Kinni awọn ayọrisi buburu lati ibi abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa?

Kiiṣe gbogbo eniyan lo n ni ayọrisi buburu lati ibi abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára. Lati pese aabo, abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa n sín awọn arun mẹtẹta ti gbogunti jẹ. Awọn eniyan kan le ni ara sisu to ri bii ìta ti ko le, oju le wu ti yoo si ri bi ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan tabi wọn le ni irora ni awọn orikerike ara bi ìta pípọ́n. Awọn ayọrisi wọnyi waye laarin awọn eniyan perete lẹyin abẹ́ẹ́rẹ́ akọkọ.

A ma n saba ri awọn ayọrisi lati apa àjẹsára ti ìta nigbati àjẹsára naa ba bẹẹrẹ iṣẹ bii ọjọ mẹfa si mẹwa lẹyin igba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára. O seeṣe ki oju wiwu tabi irora orikerike jẹyọ

bii ọsẹ meji si mẹta lẹyin igba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára nigbati ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n ba bẹẹrẹ iṣẹ.

Ayọrisi buburu bii ara sisu tabi ọrun wiwu kan ma n di bii ọjọ meji si mẹta wọn ko si le ran. Eyi tumọ si pe bi o ba ni awọn ayọrisi buburu, o ko le ko àrùn naa ran ẹlomiran.

Lẹkọọkan, ara súsú pupa tí ń wò bíi ara bíbó kiunkiun le sẹlẹ to ọsẹ mẹfa lẹyin eto abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára.

Eyi yoo ṣe iranwọ lati dena awọn ajakalẹ àrùn.

O gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára bi o ba n siṣẹ pẹlu awọn ọmọ wẹwẹ tabi ṣe itọju fun awọn eniyan gẹgẹbi ara iṣẹ rẹ. Kiko arun ìta ran awón ómode ti wọn keere lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR tabi ran ẹnikẹni to ti n s'aisan, le ni atubọtan lile fun ilera wọn. Gẹgẹbi ikiyesara, awọn obinrin gbọdọ yago fun ninu oyun fun osu kan lẹyin gbigba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR.



## Kinni ìdí ti emi ati àwọn ọmọ mi fi gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára?

O gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára lati dábòbò ara rẹ tako awọn àrùn mẹta lile. Nipa siẹ bẹ o ṣe iranwọ lati dábòbò awọn miiran ti wọn ko le gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára. Awọn ni ọmọ inu, àwọn ìkókó ti wọn keere jù lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ati àwọn ọmọde/ agba ti wọn ko le gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára nitoripe wọn ni eto ara igbogunti alailagbara.

## Ṣe abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ni oje gẹlatini?

Ni orilẹ-edeUK, a ni abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR meji eyiti on sisẹ daradara. Ọkan ninu wọn ni oje gẹlatini ti a gba lati inu ẹlẹdẹ ekeji ko ni. Bi o ba yan lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ti ko ni gẹlatini ninu, ba akọṣẹmọṣẹ nọọsi tabi GP rẹ sọrọ.

**Bi o ba ro pe o ti le ni arun ìta, ibà àti àpò ìtọ̀ wiwu ti o le gan ati ìta pípọ́n, o ṣe pataki ki o din ewu riran arun naa mọ awọn eniyan yooku. O gbọdọ:**

- Pe GP rẹ fun imọran, wọn le nilo lati s'eto fun abẹwo si ile abẹ ni opin ọjọ ki o le yago fun ifarakinra pẹlu awọn eniyan to le tete f'arako arun naa, bii ọmọ wẹwẹ ati alaboyun.
- Yago fun iṣẹ tabi ile-ẹkọ fun o keere tan ọjọ mẹrin lati ọjọ ti o kọkọ ni ààmì ara súsú ìta.
- S'eto lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára to ti jẹ silẹ ni kete to ba ti gbadun. Eyi yoo dábòbò ẹ lọwọ awọn arun mejeji yooku.

## Njẹ ẹnikan wa ti ko yẹ ko gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR?

Gẹgẹbi abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ṣe jẹ ààyè a ko gbọdọ fun alaboyu tabi awọn eniyan ti wọn ni eto ara alailagbara to le, fun apẹẹrẹ awọn to ṣe atunto ọra inu egungun tabi ti wọn n lo ògùn iro eto ara lagbara.

Bi ko ba da ọ loju ri dokita rẹ lati baa jiroro. Bi o ba ni ifidimulẹ adẹhinbọ ẹjẹ riru si neomycin o ko gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára. Bi o ba ni ifidimulẹ adẹhinbọ ẹjẹ riru si gẹlatini o gbọdọ ba GP rẹ sọrọ ki o si s'eto lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ti ko ni gẹlatini ninu.

### Irira si Ẹyin

Gbogbo awọn to ni irira si ẹyin, pẹlu awọn ọmọde to ni ikọ-fe, le ni gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ni ile-abẹ GP. Enikẹni to ba ni akọsilẹ adẹhinbọ ẹjẹ riru si abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR gbọdọ ṣe ayẹwo pẹlu oluyẹwo irira ara.

# Kinni awọn ààmì ati ààmì àrùn?

| Ìta | Ibà àti àpò ìtọ̀ wíwu ti o le gan | Ìta pípọ́n |
| --- | --- | --- |
| Iba, awọn ààmì otutu, ara súsú, oju pípọ́n tabi ẹyinju wiwu | Iba, ẹfọri ati isun wiwu ni oju | Awọn isun wiwu, ọgbẹ ọfun, igbona ati ara súsú |

## Ṣé ó lé?

| Bẹẹni | Bẹẹni | Bẹẹni |
| --- | --- | --- |
| Bii ọkan ninu marun n lọ si ile-iwosan ati wipe ọkan ninu mẹẹdogun yoo ni idiju lile. Ìta le fa iditi, aise deede, ọpọlọ bibajẹ ati ọpọlọ wiwu. Lati ọdun 2006 iku lati ọdọ ìta mẹta lo ti wa ni orilẹ-ede UK. | Biotilẹjẹpe ọpọ iru eyi ko le pupọ, ibà àti apo ito wiwu ti o le gan le fa àrùn akoran ọpọlọ wiwu ati irora oju ara wiwu, ati ti oronro nigba miiran. | Biotilẹjẹpe awọn ipo naa ko le pupọ, nini arun ìta pípọ́n l’akoko oyun le fa ailera lile fun awọn ọmọ inu, bii iditi, ifọju ati iku paapa. |

## Tani o nilo lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa?

- Gbogbo ọmọde to ti ju ọdun kan lọ gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára meji, wọn ma n gba abẹ́ẹ́rẹ́ akọkọ ni ódun kan ati abẹ́ẹ́rẹ́ keji ni ọdun kẹta ati osu mẹrin.
- Awọn ọmọ to dagba ati agba gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára meji pẹlu alafo osu kan laarin wọn.
- Awọn alaboyun gbọdọ rii pe wọn dábòbò ara wọn saaju ki wọn to loyun tabi rii daju pe wọn gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ni kete lẹyin ibi wọn.

**Ko tii pẹ ju lati gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára bi o ko ba ti gba abẹ́ẹ́rẹ́ mejeeji.**

## Nibo ni mo ti le gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára naa?

### Lati ọdọ ile-abẹ GP

- Gbogbo ọmọ to ba ti to ọdun kan si ọdun mẹta ati osu mẹrin gbọdọ gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára gẹgẹbi ara ilana-iṣe abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ni ile-abẹ GP wọn.
- Awọn agba ọmọ ati agbalagba gbọdọ kansi GP wọn lati gbaradi boya wọn ti gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára kan tabi mejeeji.
- Awọn oloyun le gba abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára ni ile-abẹ GP wọn lẹyin ti wọn ba ti bi awọn ọmọ wọn ti wọn ko ba ni akọsilẹ abẹ́ẹ́rẹ́ mejeeji

### Ni ile-ẹkọ rẹ

Awọn agunbanirọ ati ọdọ ti gba awọn abẹ́ẹ́rẹ́ àjẹsára MMR ti wọn ti jẹ silẹ pẹlu awọn àjẹsára afikun ti agunbanirọ yooku.

### Lati ọdọ iṣẹ ilera olugbanisiṣẹ rẹ

Awọn osiṣẹ itọju ilera toni ifarakinra pẹlu alaisan taara gbọdọ ri daju pe wọn dábòbò ara wọn tako awọn arun mẹtẹẹta.

## Ìta, kiiṣe isoro awọn ọmọde nikan

M ÌTA
M IBÀ ÀTI APO ITO WIWU TI O LE GAN
R ÌTA PÍPỌ́N

**Bi o ba fẹ iwifun miiran nipa MMR jọwọ ṣe abẹwo si**
www.nhs.uk/conditions/vaccinations/pages/mmr-vaccine.aspx

NHS

© Crown copyright 2022
3219250YO Yoruba 2p 75K MAR 2020 (APS)

Atẹjade Akọkọ Osu kẹfa ọdun 2016

A le sẹda awọn ọrọ inu iwe yii laisi igbaaye tabi gba ilo ara-ẹni tabi ilo inu ile.

Bi o n'ifẹ si awọn ẹda iwe pelebe yii, jọwọ kansi www.healthpublications.gov.uk/Home.html nipa lilo koodu ọja: 3219250YO Yoruba tabi foonu: 0300 123 1002, Minicom: 0300 123 1003 (aago mẹjọ owurọ si mẹfa irọlẹ, ọjọ Aje si Ẹti)

**www.nhs.uk/vaccinations**